Lagos

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI"—W. T. STEAD.

VOL. IV. NO. 170. SATURDAY, OCTOBER 17, 1925 4d

***The People's Leading Vernacular Paper.***

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO ***J. F. SICK***

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orișnisi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita :—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Waji, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Õlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹke Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumãdan

Ẹ wa wo Ile ọja wa ; A ni nkan wọnyi fun tita :—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Asọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Asọ Iș'ọșọ, Ẹro Ere Ọmọde; Ohun Ọșọ, Abẹla (*Candles*) ati ẹgbagbeje ojà miran.

A nta Mașini *Vesia*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni :— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

---

## *Electric Novelties.*

Mr. M. SADIKU has assorted kinds of Electric Materials, 2 & 3 lights, Brackets, Shades, etc., too numerous to mention.

He undertakes the contract of wiring houses at very reasonable prices.

And has also in stock louder bells complete with wire and Salamoniacal ready for connections. Call at 18 Ọbun Eko Street, Lagos, for your selection.

*P.O. Box 378.*

---

## WHO SAYS TOOLS?

Ọgbẹni J. O. BANKỌLE ti Daddy Alaja *Street, Lagos,* ni wabiwọsi irin ișẹ *Carpenter*, fun tita, awọn irinșẹ bĩ Kọkọrọ, *Rachet Braces, Coffin Handles, Wall Papers*, ati bẹbẹ lọ. Ọpọku ọyọku ni owo wọn.

Jòjò nyaju ni wọn.

# OPEN AGAIN

## AND IN

# FULL SWING

# LEVER STORE

*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.

ONINI BABA EWU.

Ọgbẹni D. L. Oshodi ti 36, Idoluwo *Street, Lagos* ni orişirişi *Ivory Coat & Trouser Button* (Onini) fun tita kosi aşọ ti ko ni *button* to yẹ. O si ni wabi-wọsi ero-ija *Tailor* (*Tailors Trimmings*) ni tita bakanna; o si nfa'şọ şe *button* (*Press Coat Buttons*) ki awọn af'aşọ-dara (*Expert Tailors*) maşe jafara lati ba rà tiwọn; ọpọku-ọyọku ni ọja meremere wọnyi.

## GBOHUN-GBOHUN.

—:o:—

ẸNI A BA TA KA FI R'ATUPA, O NI ON AJITAN'NA WO LORU! ŞIỌ!!

Ede ti a le lo fun Dokita Adam Oyinbo Onişegun ti ọ̀jẹ Adele awọn Dokita Ọba nilu yi nisisiyi leyi; nitori o jẹ ohun to yani lẹnu pe gẹgẹ bi awa Enia Dudu apa ibi ati Oyinbo ti ndu ni sã yi lati ma wa ni irẹpọ ati ni ajumọ fẹran ara ẹni, Dokita yi fi ẹnu kọ ninu Wãsi ti a gbọ pe, o şe ni Şọşi C.M.S. ti Ebute Mẹta ni alẹ *Sunday*, ọjọ kẹrin oşu yi, pe ohun ti o yẹ gidigidi loju on ni ki Enia Dudu wà gede, ki Oyinbo si wà gede pẹlu gẹgẹ bi aşa wọn ni ilu Saro. O ni ni ọna irufẹ eyi awa ara ilu (*Natives*) ko ni le ma ko arun ran awọn Oyinbo mọ.

O tilẹ gboju gbaiya pe gbogbo awa Enia Dudu ni ohun alaimọ, ninu Iwe (*Text*) ti a sọ pe o yan ninu Bibeli eyini ni Kọrinti keji, ori kẹfa, ẹsẹ kẹtadinlogun (II *Corinthians* 6. 17); ti o ba jẹ otitọ leyi gẹgẹ bi a ti ri ka ninu Iwe Irohin *Nigerian Advocate* ti ọjọ keje oşu ti o jade ni *Tuesday* ọsẹ yi, a fẹ bi Dokita Oyinbo na lere gbolohun ọrọ meji mẹta.

Ekinni:—Nigbati Dokita Adam yi mọ pe ohun ti ọkan on wa ni ki Enia Dudu ati Oyinbo wa lọtọlọtọ eyiti o njẹ *Segregation* lede ilu iya rẹ ki lo mu gba işẹ Dokita Ọba wa si ilẹyi? Kilo si mu ki o ti ilu majaku ilu rẹ wa silẹ Enia Dudu nibi?

Ekeji:—Ki lo ya apari rẹ lori to nmu ọ̀kun lodo ti o fi dogun pe o lọ si Şọşi ti o jẹ pe Enia Dudu ni Alufa ibẹ, Enia Dudu si ni Mẹmba ibẹ şe lati lọ bu ati Alufa ati awọn Mẹmba ibẹ şakaşaka pe nwọn jẹ alarun lara bi igbo etile.

Ẹkẹta:—Dokita Adam ha ro pe on gã ju Edward Arẹmọ Ọba ti o wa si ilẹyi ni oşu mẹfa sẹhin lọ ni, ẹniti ko kọ̀ lati gbà Enia Dudu ti a ba tọka si; ti ko si tun kọ lati wa ninu Agbo Ijo kanna pẹlu wọn; a ko ma gbọ pe ori fọ Arẹmọ Ọba na, bẹ si ni ẹdọ ko rin titi o fi fara yi awa Enia Dudu l'Eko nibi titi de ọna Kano, titi o fi lọ?

Ẹkẹrin:—Njẹ gbogbo arun karun bi arun ẹsẹ́, arun jakutẹ, arun ogodo-Oyinbo ti o mbẹ nilu Oyinbo, awa Enia Dudu mà lo ko ran awọn ara ilu (*Natives*) ibẹ?

O şe, o pọ̀, ai s'enia ni Tẹpọnna lo mu ka fi Kariọran jẹ Iyalode; ai ri enia jẹ Adele Olori Dokita Ọba lo mu ki Ijọba fi Ọgbẹni ti ko ni ifẹ awa Enia Dudu, awa ọmọ abẹ Ọba King si Ipo ribiribi bayi, ipo ti o jẹ pe iru awọn bi Ologbe Oyinbo Dokita Ọba Oninure wọnyi ti wa ri nigba lailai; awọn bi Ologbe Dokita Henry Strachan, Ologbe Dokita Hopkins ati awọn Oyinbo Dokita Ọba jakan jakan miran. Ọrun oni a san wọn.

Lakotan a fẹ ki Ijọba şakiyesi irufẹ Iwasu ti Dokita ti o npe ara rẹ ni ọmọ lẹhin Kristi yi şe, ki nwọn si wò wò bi Dokita na kọ fẹ joye daran-daran eiyẹ ti nmusan.

A dupẹ pe oloto awọn Oyinbo to wa lara wa nibi ti ifẹ ati ma ba awa Enia Dudu ṣe nkan pọ ko dinku. Bi ẹnikẹni da ẹgbẹ Parakogan Oyinbo nilẹyi ( *Lagos Chamber of Commerce* ) tabi Igbimọ Aṣofin Ijọba, ( *Legislative Council* ) tabi Igbimọ Munisiba, ( *Town Council* ) a o ri toyinbo tenia dudu bi nwọn ti nfi di po di pọ ji rọ̀rọ̀ ọrọ ilu wa nibẹ. Dokita Adam mā mà dāmu ara rẹ o.

ANIMỌTU O DI GBERE!

Gbukẹ la gbọ iku Animọtu Ṣadia, ọmọ Ọgbẹni wa Abudu Ramonu, ni Opopo-nla ( *Broad Street* ), ni aṣalẹ ọjọ Atini ( *Monday* ) ijọ kẹrinla oṣu yi. Ọmọdebinrin yi jẹ oniwapẹlẹ, ki ṣapọn, ki binu, o da bi Iya fun baba rẹ nile. Ki Oluwa ki o tu baba rẹ ninu. A ki Bale rẹ, Saka Misiun, awọn ẹbi rẹ, ati Salamọtu Oki, ọrẹ rẹ, ẹ ku ifarada.

---

## "EKO AKETE" LAW REPORT.

[ Lati ọwọ ATOLUGBOKUN. ]

Mo tọro gafara lọwo ẹnyin ọkawe mi ni ọsọsẹ nipa aile jade mi ni ọsẹ to kọja, idiwọ lo njẹ be, bi mo ba gbiyanju ni ọse yi papa ni, ẹ ko ba ti gbọ ohun mi ni ọsẹ yi. Obaginji Ọba Ogo ko fun gbogbo wa ni alafia ara, *Aṣẹ*.

Ni ọjọ *Friday* ijọ keji oṣu *October* 1925. Niwaju Ọlọla Adele Adajọ Agba Ogbẹni A. F. C. Webber. Ni agogo mẹsan ni Lọya Zizer gba ina lọwọ Lọya Shyngle ẹniti o ti nsọrọ bo wa nipa ọrọ Eleko lori ti *Habeas Corpus* na Lọya Zizer ni ohun to ku lati sọrọ le lori ohun ni pe bi Kotu ilẹ yi ba ni agbara de ibiti Eleko wa. *The point to argue is the subject of Jurisdiction* o ni ibiti o wun ki Eleko wa awọn ko fẹ mọ yẹn, ohun ti awọn bere fun ṣa ni ati mu wa sile ko wa so ten u rẹ ( *we apply for writ of Habeas Corpus* ) o ni nitorina ki Adajọ gba ofin wọnyi yẹ wo. L.R. K.B.D. 1910 Vol. 2 P 579. Your honour should look on the defence in the case cited. I refer to Halsbury P 45 as to the extensive of jurisdiction I also refer to the same Halsbury P 46, Vol 10.

Court :—You ask me to produce person whom I have not got in my possession.

Your Honour :—I refer to Appeal Case 872 P 326 that is a case of a man who has control.

Lẹhin eyi Lọya Zizer sọrọ pupọ o si ma ... riṣi ofin wa lati fi han pe Kotu yi ni aṣẹ de ... Eleko gbe wa ni ọhun.

Lẹhin na ni Agbẹjọro Ọba fesi pada.

Adajọ ni iwọ Lọya Zizer on nla ka awọn ofin fi si iwaju on wo dada ki on to le di ẹjọ On a si kọ idajọ wa. Ṣugbọn ti ofin to mu wa ... ẹjọ yi on fa iwe iyẹn ya. *The rule is struck out*.

Ni ijọ *Monday* ijọ kejila oṣu *October* 1925 ... waju Ọlọla Adele Adajọ Agba Ogbẹni A. F. ... Webber ni Kotu Ganran.

### JUDGMENT TABI IDAJỌ

REX *versus* YESUFU ALABI

Ẹjọ odaran yi ni eyiti Adajọ Kotu Ọlọpa ... nipa Yesufu Alabi awa M. to Kekereogun ... Adajọ na ni ko lọ si ẹwọn oṣu mẹfa. Ọdaran ... gba Lọya Thompson wọn si ro ẹjọ ... ni ganran. Adajọ ni gbogbo ofin ti Lọya Thompson mu wa siwaju on ati ọrọ rẹ on gba, ... ohun to jẹki on kọ, ni pe o ni liti so nkan ... niwaju Adajọ to kọkọ da ẹjọ na ni Kotu Ọ... ko to mu wa si Ganran. Nitorina on ti ... Kekere da abẹ ge. Ki Yesufu Alabi ko yara ... mu ọna ẹgba ẹwọn pọn ni wara ṣeṣa.

*Re* ELEKO WRIT OF HABEAS CORPUS

Adajọ ka idajọ rẹ lori ọrọ Eshugbayi Eleko ẹniti Ijọba mu lọ si Ọyọ. ohun ti Adajọ ... ni pe on ko ni Aṣẹ de ibiti Eleko gbe wa, ... on kọ Aṣẹ ti Lọya Eleko fi siwaju on, on si kọ ... fun wọn ni Aṣẹ ati mu wa. *Rule discharged, ... refused*.

Ni ijọ *Monday* ijọ kejila oṣu *October* 1925 ... waju Adajọ Kotu Ọlọpa Ogbẹni M. C. Greene.

POLICE *versus* ARTHUR MAYNE

Ẹsun ti Ọlọpa fi Arthur Mayne sun fun ... o ji iwe owo kan ti o jẹ Ogoji ponwn ati ẹsun ... ni pe o gbiyanju ati fi ọna eru gba ogoji pọnwn ... stealing promissory note value £40 attempting ... obtain £40 by way of false pretences.

Ẹjọ Arthur Mayne jẹ ẹjọ to wa larin on ... Aya re kan to ti ni ri, tioruko njẹ Moriamo Anjọlaya.

Mo lẹ fun nyin ni itan ẹjọ yi niba ja... Lẹkinni Adajọ mu Arthun Mayne, Moriamọ Anjọlaya ati awọn Kurumọ ti wọn ni wọn lọ ... ni Ebute wọn si ji Cocoa. Ẹjọ yi pari, wọn si ... ninu ẹjọ na. Lẹkeji, Arthur Mayne pe obinrin ... yi ni ẹjọ nipa *Motor Car* eyiti o kan J. Olu. Johnson ... awọn Arthur Mayne jare ẹjọ yi. Lẹkẹta Arthur ... Mayne pẹlu obinrin yi wa si Kotu nipa wipe wọn ... nbu ara wọn ni tà gbangba. Adajọ ni ki wọn ... lọ. Ẹkẹrin ni yi. Arthur Mayne ni on ... Mọriamọ Anjọlaya lowo ogoji pọnwun (£40) ... pẹlu aburo rẹ obinrin ki wọn le ri owo san ...

Ọpa-alaye ẹjọ ile, ti wọn nro ni Kotu, Arthur Mayne ni on ti ya ni pọwun mej lelọgbọn ri ti on ko ri gba, on wa sọ fun wipe ki wọn ṣe iwe si, ṣugbọn on ko fẹ ki orukọ on han ninu iwe na, lehinna awọn fi orukọ Agbetọba si, Mọriamọ pẹlu aburo rẹ fọwọ si iwe na. on li on ba wọn ṣe iwe na, nigbati o pẹ diẹ Agbetọba pe on ati Mọriamọ o gbe iwe le Mọriamọ lọwọ, Mọriamọ si mu iwe na le ohun lọwọ, on si toju rẹ nitori awọn mejeji lo mọ ohun to wa nidi ọrọ na, nigbati o ya ti Arthur Mayne fa Agbetọba ti Agbetọba fa Mọriamọ ti owo yi ko jade. Ni Arthur Mayne tọ Lọya Harrison lọ pẹlu iwe owo yi, ni Loya Harrison ni ọrọ ti iwọ Arthur Mayne sọ ko to tẹle ayafi to ba la pe Agbetọba wa, ko wa sọ tẹnu rẹ, Mayne pe Agbetọba, Agbetọba lọ si ọdọ Lọya Harrison Lọya yi si fi orukọ Agbetọba kọwe si Mọriamọ lehin ti Mọriamọ ri iwe gba tan, lo wa lo si ọdọ awọn Ọtẹlẹmuyẹ ni awọn ẹlẹgiri ba lọ mu Arthur Mayne ti ọrọ yi fi di ẹjọ. Ki Arthur Mayne to la gba Lọya Thompson fun ẹjọ rẹ. Nigbati Adajọ wa'di ọrọ na, o ni Agbetọba sọ ni Kotu wipe on ko fi owo ti on ya enikẹni, nitorina on da Arthur Mayne silẹ ko ma lọ ko jẹbi; ṣugbọn ki Ọlọpa mu iwe owo yi pada fun Mọriamọ Anjolaya. O ni ati ọtun ati osi ko si eyiti o mu ọwọ to mọ wa si Kotu. Bi ẹjọ yi ti pari si ni yi o. Arthur Mayne bi ṣiṣi ko ba dẹhin lẹhin rẹ, o ko dẹhin lẹhin ṣiṣi. Ẹsọ ko to ẹ.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATOLUGBOKUN.

## THE YOUNG ANSAR-UD-DEEN.

58, Breadfruit Street,
Lagos.
11th October, 1925.

The Editor,
*Eko Akete*,
Lagos.

Sir,
May I thank you for publication of the attached copy in your paper of this week.

Yours sincerely,
BOONYAMIN KASUMU,
*General Secretary*,
Y. A. D. Society.

THE YOUNG ANSAR-UD-DEEN SOCIETY.

58, Breadfruit Street,
Lagos,
11th October, 1925

The Editor,
*Irohin Eko Osose*,
Lagos.

Sir,
It has been brought to my notice that in your issue of the 3rd instant, certain "Kuluso Eko"—A Yoruba Correspondent of your paper—reporting on the recent Harvest Sales held by the members of the Fourth Division of the Young Ansar-ud-Deen Society, stated that this Society belongs to the Jamat Party of the Central Mosque, Victoria Road Lagos

I hasten to correct that statement, and to point out that the Y. A. D. Society does not belong exclusively to any of the Parties or Divisions of the Lagos Muslims. On the contrary it is an all-Lagos-Muslims Society and its members are drawn from all sections of that community.

I should therefore be thankful if you would kindly cause this letter to be published in your issue of this week as the Yoruba words "INU IJỌ MỌSAL-ṢI JIMỌ NI AWỌN WA" occurring in "Kuluso Eko's report" are calculated to create an impression prejudicial to the non-sectarial policy of my Society.

Yours sincerely,
BOONYAMIN KASUMU,
*General Secretary*,
Y. A. D. Society.

## IROHIN IKORODU.

### IJỌ ỌMỌ IBILẸ.

[*Lati ọwọ* Bọṣere Ẹlẹpẹ.]

Si Oni 'we-irohin "EKO AKETE."

Ọwọ nyin a r'oke o,

Ko si bo ti ri ni Isin Ikore ti a ṣe ni Ṣọṣi Ọmọ Ib lẹ *African Bethel Church* ni ọjọ kẹrin oṣu yi. Awọn Ẹni-ọwọ meji lo wa lati Eko fun Isin yi, ati Ọgbẹni O. Taylor, Atẹduru Ijọ *Africa* ti Eko, Alufa-Agba Rt., Rev., Supt. J. S. Williams ati Alufa A. A. Cole.

Ẹru fẹrẹ ba ni, nigbati a ri Alufa Cole ni ọjọ Satide ti nwọn gunlẹ si Ikorodu pẹlu ẹwu awọn Ologun (*Scout Uniform*) bi ko ba si pe ẹniti a mọ bi ẹni mọ owo ni, ẹru iba ba wa, a fẹrẹ le pe Alufa wa na ni Rev. Major Cole.

Nipa Ọgbẹni ti a ti rohin rẹ pe ko ni ẹnikeji ninu Onigbagbọ Ikorodu nipa orin kikọ, Ọgbẹni E. Ọmọṣanya Dawudu ni kọ ba-nsa orin tobẹ ti Ọgbẹni kan fi gbagbe ara rẹ, ti o si dide fo, ti o bẹrẹ si jo; kosi si ẹniti o wa nibi Isin yi, ti ko gba fun Ọgbẹni Dawodu a fẹrẹ le sọ wipe orin kikọ yi ni nwọn fi mu iyawo kan Ọpẹlẹngẹ wa fun Ọgbẹni na, ni ọjọ na gan 4/10/25. Ki Baba maṣai toju ile ati ọna rẹ, ẹnyin agba Ijọ iba dara pupọ bi ẹ ba le yi kọla Emanuel O. Dawodu sẹhin, ki o ba tubọ ri aye dabira ti o wa ni inu rẹ.

A ki nyin, ẹ ku inawo ọjọ a si ki awọn enia Ọlọrun ti o ti Eko wa ki Oluwa ki o pẹlu gbogbo nyin—Aṣẹ.

ISAAC KALẸJAIYE, ỌRUN 'RE.

Ọgbẹni yi jẹ Ọmọ-ibilẹ Ikorodu fanfau, o si jẹ ọmọluwabi enia, o fi ilu Ikodu silẹ ni ọdun 1905, ninu ọdun yi ni o si gbe iyawo, o wa si Eko ninu

odun yi lati wa wa onję ōjọ rẹ, ki Ọlọrun to pese fun u ni Ọgba Alarun (*Lagos Colonial Hospital*) ibẹ li o si wa titi ọjọ iku rẹ, papa ọgba yi ni Ọgbẹni na sun orun ikẹhin ni ọjọ kejidinlogun oṣu *July* odun ni 18/7/25; ipo rẹ si ni 1st Class Nurse, o ti wa ni (*B Ward*) ki a to tun gbe e lọ si (*D Ward*) ninu ọgba na.

Ni gbogbo akoko iṣẹ rẹ yi o jẹ ẹniti o fẹran ẹnikẹni, papa ara ilu rẹ, ni akoko ti o wa ni ibi iṣẹ yi, ko si ara Ikorodu kan ti ko nrohin ãjo rẹ tobẹ ti nwọn fi fun ni orukọ kan eyini ni—Asiki, (Isaac).

Awọn Ọgbẹni Samuel T. Sekiri, J. B. Awojọbi, J. A. Ọdunlami mọ riri iṣẹ rẹ ati ọpọlọpọ awọn ti a ko le daruko tan ni akoko ti nwọn wa ni Ọgba Alarun.

Opo nla kan ni o ya lọ kuro ninu Ẹgbẹ Jos: M. Ṣonubi, awọn ti o mọ riri rẹ, bẹni ki iṣe ibanujẹ diẹ lo mu ba awọn Ijọ Wesley Ikorodu, o si jẹ Mẹmba kikun ni Ijọ Wesley Ọbun Eko, ko si ẹniti ko ya lẹnu nigbati Ọgbẹni J. S. Thompson nwasu igbesi aiye rẹ ni Ijọ Wesley Ikorodu, kosi si ẹniti ko bu sẹkun nigbati Ọgbẹni Owen S. Dawodu gba adura fun awọn ẹbi Ọgbẹni yi ni ọjọ keji oṣu *August* ni ile nwọn ni Ikorodu. Ki Baba ti o ṣe iṣẹ rẹ b'o ti wu U, maṣai tọju awọn ọmọ, iyawo ati gbogbo awọn ẹbi rẹ. Amin.

## JEFO-JEFO.

Arun yi ṣẹṣẹ wọ ilu Ikorodu, o yara pa enia gẹgẹ bi awọn ti o mọ ọ ti sọ, ki iṣe Magun bẹni ki iṣe Masọ ṣugbọn ẹlẹya rẹ fẹrẹ ju ti iwọnyi lọ, nitorina a bẹ ẹnyin ọdọmọkunrin wa pẹlu awọn onidi nla, awọn ti gele ori wọn ju Lãni Ladani lọ, bi ẹ ko ba gbọ ẹṣu Jefo-jefo yio sọlẹ nidi nyin.

A si ki Ọgbẹni Daniel O. Madariọla ara Itun Mẹkọ, ẹ ku ewu. Kiki ti a ki Ọgbẹni yi ni pe, bi ko ba si Ọlọrun ti o tete gbe ija silẹ larin on pẹlu onidiku ba-nti-banti kan ti o npete ati fi ṣe aya ni, ẹṣu jefojefo iba ti ṣe ni agbole wọn, ṣugbọn ọna ara ni iṣẹ Baba, bi ko ba da Ọgbẹni yi loju, ki o lọ wa idi ẹsu yi ni Ebute Iga loni.

A ko le ṣe alai ma fẹ obinrin ṣugbọn iba dara pupọ bi awọn enia wa ba le baralẹ, ki nwọn wadi obinrin ti nwọn ba ma fẹ. Bi enia ba tori obinrin kanṣoṣo ku, dajudaju Ọlọrun yio ba oluwarẹ ṣe ẹjọ bi o d'ọrun.

Awọn ọnigele ọpa meji-abọ ti a wi yi, nwọn ni ãjo pupọ, nwọn a si ma farahan bi ẹnipe ifẹ ti nwọn ni si oluwarẹ lo tobẹ, ṣugbọn bi oluwarẹ ba mọ ọ l'ẹwa ti o si yanrun, nkan de, jefojefo ko si jina si oluwarẹ, nitoripe bi o ba pade obinrin yi ni Iṣẹlẹ, ki o to ṣeju pẹ o ti de Ebute Iga, bẹni awọn ti o ba ri ni Ijomu yio tun ma sọ fun ẹ pe awọn pade iyawo rẹ lọna, bi enia ko ba sọ ara rẹ ti o nsọ pe Ọlọrun yio sọ on, ẹṣu jefo-jefo nbẹ nidi rẹ. Ẹ ma ṣọra.

O di ọsẹ iwaju ki a to sọ diẹ nipa awọn ọ[illegible] Maṣa-nlọ (*Martial-Law*)!

Emi ni ti nyin nitotọ,
BOṢERE ẸLẸPẸ.


**The West African Soap Co. Limited**
**APAPA, NIGERIA**

*Manufacturers of*

**NEPTUNE**
PALE SOAP

**BUGLE**
PALE SOAP

**MAGNET**
CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

**P.O. Box 522**
**Lagos**
**Nigeria**

F 393


Mrs. Beckley of No. 53 Broad Street begs to announce that she has started cake-baking of all kinds; ever ready to serve!

GUARANTEED

THE RALEIGH

FOR EVER



# RALEIGH

## THE ALL-STEEL BICYCLE

MILLER BROS. (L'pool) LTD.,

LAGOS.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, OCTOBER 17, 1925.

## B'ỌMỌDE MỌ'WỌ WẸ, A BA AGBA JẸUN.

Sisojude ti a tun gbọ pe ọrọ *Prince* Eşugbayi sojude ni Kotu Ganran ni *Monday* ọsẹ yi jẹ ohun ti o dun ẹnikẹni. Ọrọ tabi ẹjọ ti Adele Adajọ Agba ta laiya yi ni pe ki Kotu fi aşẹ si mimu Eşugbayi pada bọ wa silẹ lati wa sọ ti ẹnu rẹ.

A fi àpà-bòbõ afọnu-fọra a-fosi jo dùndùn ni ko ni şe "şai" si ogidinleje owo ti awọn enia ti nna si ẹjọ yi lati iwọn oşu meji tokọja: ninu gbogbo orişirişi ẹjọ ti awọn Loya ti a gba fun ẹjọ na si ti nro bọ, kosi ọkan to murọ̀. Nigbati a si fi ero lu kilo ti gbe ki eyi to ri bẹ̀ ohun ti o sọ si ni lọkan nipe, boya gẹgẹ bi o ti jẹ pe Ijọba kò mu ọrọ na lọ si Kotu latetekọşe lo jẹ ko ri bẹ̀; ẹnyin enia wa yio si ranti pe Agbara aşẹ Ọba King ni Ọgbẹni F. M. Baddeley Adele Gomina lò ninu Akanşe Iwe Irohin Ijọba ti Adele Gomina na fowọ si nijelo, ki o to di pe a mu *Prince* Eşugbayi lọ sẹhin ẹ̀kùn.

A şe bi Ijọba ri Kotu nilẹ, ki nwọn to gbe ọran na gba ọna miran; ni gasikia, Ọba lo to ehin erin fọn; ko si bãle ile ti a le şi nidi kuro ni ile rẹ ni şaşadidi ti ẹnikẹni ko ni kanu fun; ki a şẹşẹ wa sọ ti şişi Olori ilu nipo lọ si ilu okere gẹgẹ bi *Prince* Eşugbayi.

Ẹnyin ara, ohun ti o yẹ ki ilu gbidanwo rẹ ni mimuşe nisisiyi ni ẸBẸ̀. Ẹ jẹ ki a tun ọwọ wẹ bi ọmọde, ki a si mọ Ijọba ti nwọn jẹ Agba wa ba jẹun; ẹ jẹ ki a tete magba l'ẹgbọn; ẸBẸ, ẸBẸ, ẸBẸ, lo tọ, ẸBẸ. Bi a ba bẹbẹ tọ̀wọ̀ tọ̀wọ̀ pe ki Ijọba King ma şai fi oju anu Rẹ wo *Prince* Eşugbayi, ki o si fi oju anu Rẹ wo gbogbo awọn şàşà wẹ̀rẹ̀ ti a mu ki o dà silẹ̀ lọs ıngangan laiku ẹ̀kìrì, ki nwọn mu bọ wa si itosi; a ro pe eyini ko ni buruju, firi firi şa san şẹ kolombo

Ara Ẹ jẹ ka m'Ẹbẹ o,
Ẹbẹ l'ẹ̀yẹ̄ ju,
Ẹbẹ l'ẹ̀yẹ̄ ju, laiye
Ẹbẹ l'ẹyẹ ju
Ara Ẹ jẹ ka m'Ẹbẹ o,
Ẹbẹ l'ẹ́yẹ ju.

Ko si si ẹniti o le sọ po GBIGBOJ[...] GANGAN lati tọrọ nkan ribiribi lọ[...] Agbalagba jẹ ohun to dara; loju wa [...] yi kuro ni ti wipe şe nigbati Oloye k[...] gbe ẹjọ ilẹ rẹ lọ si ilu Ọba nijọ kinni, şe[...] jori ẹjọ na nigbati ko ri itẹlọrun ni K[...] ibi, otitọ leyi; Oloye ti a nwi na lo k[...] gbe ọran rẹ lọ si Kotu n'ilẹ yi. Şugbọn [...] ha ni ti *Prince* Eşugbayi ri nişiwaju [...] Ọrọ mejeji yatọ sirawọn; ekinni ti [...] Oloye papa wa, nitori on lo gbe ọrọ il[...] lọ si Kotu: ekeji jẹ ọrọ Ominira enia [...] Asia Ọba King, ọwọ Aşoju Ọba King nib[...] ni eyi si ti wa pẹlu; nitotọ awọn Lọya [...] le mọ ayinike ayinipada ninu ofin Oyinbo[...] kiyesi o, ofin Oyinbo ni a pẽ o, ki işe o[...] ti awa Enia Dudu; şugbọn nwọn ha [...] ayinikẹ-nike tabi ayikọrọyi-kọ bi? P[...] nipa ọran yi, ẹ sa gbọ ede Lọya Oyi[...] kan ti a sọ pe o lo fun ogbogi Lọya E[...] Dudu kan ni'lẹ yi ni sũ kan, nipa ọrọ ka[...] nwọn nfa mọ ara wọn lọwọ ni Ganran, a [...] pe Oyinbo nà lọ ibosi gbẹ pe "*We ma[...] the Law*" iyẹn ni pe "Awa Oyinbo l'o[...] ofin;" irọ ha ni bi? Gbolohun kan A[...] leyi o to Awo şe.

Ilu ẹ jẹ ki a ş'ẹbọ ẸBẸ,
Ẹ jẹ k'a ş'etutu.

Ati pẹ l'aiye ko to nkan, ETUTU lo[...]
Ẹnit' o m'etutu agba ni yio tẹlẹ pẹ!!!

Awure nyin o!

---

### Thanks for Sympathy.

Mr. and Mrs. Akin Oni-Orisan and family [...] to return their sincere thanks to all who either [...] personal calls, letters or telegrams, and otherw[...] have sympathised with them on the occasion [...] the "Home call" of their beloved fath[...] EMANUEL IDOWU ONI-ORISAN, who exchang[...] this mortal life for immortality, at his reside[...] 24, Agoro Street, (*Ereko*) on Sunday night, [...] 4th instant.

## IGA AWỌN OLOYE OLỌTỌ.

### "A KI 'ṢẸWE TA DA GBESE."

[*Lati ọwọ* KEKERE ILU.]

Si Oniwe-Irohin *Eko Akete.*

To to o!

Iwe wa ọsẹ yi, Oloye Eletu Odibo ati awọn isọngbe rẹ ni a fẹ ko si nitori atubọtan Eko, ati atubọtan Iga wọn di ọwọ wọn. Ni iri ti a nri nkan si, awọn kanna ti nwọn ṣeṣu ṣe Ilu ni oṣu kẹta ko yi ti dẹhin lẹhin ilu. O si da oi ọran edi. Bi ko ba ṣe bẹ boya a ba ti ri idayi ana. A tọrọ gafara o.

Ko dede. Iwe *African Messenger* to njade lati igbati Ọba wa ti di ẹni wiwa lọ ko ṣe ikọ, ko ṣe igba ni. Ti ati ẹnu ọsẹ kẹta si wa buaiya, nigbati a ba nsọ pe awọn Oloye oloto ṣi nta kanrangbon si Ijọba, pe nwọn nṣefuja nwọn ko fẹ lati busa fun Ijọba, ẹnikẹni mọ pe igbẹhin agbako bẹ ko le sunwọn, nitori bẹni a ṣe fẹ ba awọn Ojoye wa ti a daruko sọrọ, nipataki Oloye wa atata, Eletu Odibo, Ọga awọn Ojoye Ilu loni.

Inu wa dun nigbati a ka iwe *Advocate* to jade ni ijọ Atalata, ṣugbọn larin rẹ na, a mọ sinu pe ero rere bẹ yẹn ko ni wọ awọn ti nwọn bawi lori; bi o si ṣe ohun ti nwọn ita gba daro awọn oniketa, onirikiṣi, ko ni jẹ.

Ṣugbọn tani le so pe asiko ko to ki Eko toro diẹ? Tani le sọ pe ibiti ija de yi ko to fi adegẹ de ija na? Ire ilu ni a nwa. A o wa fuja fuleru. A o wa "Emi ni mo wa mbẹ". Njẹ ki lo dara bi pe ki awon to fi iyikọro yi wa molẹ ki nwọn mọ pe bi igbati bo si awọn lowọ yi ki awọn to le ri i lo awon ni lati fi lakaye ti i nidi. Ṣugbọn kẹ, bi kekere ko gbọn ki lo ṣe gigun o!

Njẹ, nitorina, ki yio dara bi Oloye wa, Eletu ba wo ti ile Oye gbogbo to duro ti Eleko ki o da a ro pẹlu awọn isongbe re ki nwọn ran ẹnikan keji Ọgbẹni wa Buraimo Igbo lọ si ile Ọyọ lati tọrọ iyọnda Ọba Eleko fun gbogbo Oloye, saraki ati t'ọmọde t'agba ilu to duro ti i titi di ọjọ oni?

A ṣe alamori yi nitori a ri wipe ọrọ awọn Oloye wa ṣẹ nfalẹ ju, awọn onirikiṣi si nwa lati da si wọn lọrun. Ẹniti ko ba ri si eyi ki oluwarẹ ṣe suru yẹ awọn iwe *African Messenger* atẹhinwa wo kinikini ki nwọn ro ohun ti awọn alakoso-ilu le mu dani lẹhin ti nwọn ba ti ka iru ọrọ ti iwe na nsọ; a si tun fẹ ki awọn to ba ni kọyi-koyi ki nwọn tun ranti pe bẹ ni iwe bi meji-mẹta mi sọ nigbati ọrọ a sin Clifford a ko sin i ṣi wa ni poro-poro! Ipo ti awọn Oloye wa nigbana pẹlu Ijoba to mu ọna wa fun awọn to ṣe iṣe wọnyi lati ta jamba ti nwọn ta fun Eleko. Ipo kanna ni nwọn ṣi wa di isisiyi. Bi Ijoba ti ri pe nwọn ko yi pada, nwọn ko si tọrọ aforiji ti Balẹ ni nwọn ni lati tọrọ, ti awọn ti nwọn ro ti wọn si wa nsọ pe nwọn ko nani Ijọba, sibẹ ko ha tọ pe ki a tun ọrọ na ro ka wa worọkọ fi ṣ'ada?

Yio dara pupọ ti awọn Agba-gba ba le ro ọrọ na jinlẹ, ki nwon gba ọrọ omugọ wa yi yẹwo fun anfani awọn Oloye wa. Iduro ti awọn Oloye duro, iduro, duro s'otọ ni. Iduro ọmọluabi ni. Ṣugbọn a ki ṣowo omi ki a padanu o!

Ọrọ na so ọgbọn kọ, ṣugbọn ti a ba ro siwa ro o sẹhin a o ri i pe a ko le da ilu ṣe lai ba Ijọba ṣe pọ. Ki a ma ri iwoyi ana, o yẹ ki a tokere mu ikan ṣe. Awọn tohun ko ni ṣe. Awa ti a si mọ pe ẹsẹ Ijọba gbopọn ni lati busa fun wọn lakoko ki a ma jẹ iya mẹta oru.

A tọrọ aforiji a si juba awọn agba. Imọran ti a mu wa niyi o. Ki Ọbangiji jẹ o jiṣe o!

KEKERE ILU.

---

## Open Letters.

### To Celebrities, Notorieties, etc., in Different Walks of Life

**No. 55.**

To

DR. THOMAS BLANE ADAM,

*Acting Director of Sanitary and Medical Services,*
Lagos, Nigeria.

Misguided Physician,

I blush to read of your Segregation Sermon which you were said to have delivered in St Jude's, Ebute Meta, on Sunday the 4th instant according to the *Nigerian Advocate* of the 7th instant.

The Chapter of your alleged text viz:—II Corinthians Chapter 9 as noted in the journal was, I believe, misquoted for II Corinthians, Chapter 6, Verse 17; but the context, viz:—"Come ye out among them, and be ye separate, and touch not the unclean thing" evidently betrays you as a man who although not ashamed to leave his country 4000 miles away, to seek his bread-and-butter in blackman's land, with a personal emolument of £1,500 *plus* £300. duty pay, whatever this latter sum may mean in official terminology, yet does not scruple to preach segregation even in God's Temple on a lame plea, viz:—that "segregation was necessary between Whites and the Natives.........in order to avoid the possibility of infecting the whitemen with the plague carrying germs."

Am I far wrong to say that you by implication, branded us Africans in this part of the world, loyal subjects of His Majesty the King, "unclean thing" as observed in your text?

Now that White and Black, with particular reference to this country, are fostering, very vigorously, as never before, the spirit of true BROTHERHOOD between them, Rudyard Kipling's dictum "East is East, and West is West, and never the twain shall meet," notwithstanding, for you apparently an Apostle of suffering humanity to be thus engaged in widening rather than in bridging over the gulf of race-hatred for reasons best known to yourself, is neither politic nor wise.

You will doubtless on reflection, agree with me that your sermon in this respect is nothing short of a GOSPEL OF DESPAIR.

Now, then, Thomas Blane Adam, it is high time you bury THE OLD ADAM in you.

Cheerio ! ! !

EKO AKETE.

---

## *THE EDITOR'S OBSERVATORY.*

### Making hay while the sun shines.

Some useful work, we learn, has been done by the Committee for the Reception of our new Governor, of which Mr. Adeyemo Alakija is the Secretary : two meetings of *tete-a-tete* nature have been held and from all accounts, it is said, a measure of success is noticeable. This is as it should be.

### Well-done, Scoutmaster.

Little did we think, when Scout movement which is now almost universal in its scope, was being introduced to this country as an experiment, perhaps, some years ago, that the venture could prove so attractive—to say nothing of its disciplinary effect—to our youngsters as to make it recognised by "the powers that be." The *Nigeria Gazette* of the 8th instant (see page 619) contains a List of Recognised Troops of Boy Scout in Nigeria that would do credit to a Wellington or a Kitchener, and it is gratifying to note that the name of the person which tops this List as Scoutmaster, 1st Lagos Troop, is that of Mr. George I. Phillips, an African, of the Boy Scout, C.M.S. Grammar School (Lagos.) In this connexion we learn that at the last Scout's Concert which was held at the Glover Memorial Hall, on the 3rd instant, Mr. Phillips justified his appointment as Scoutmaster, and received the congratulations of the audience

Mr. Phillips has held the following offices in respect of Scout movement :—

Scoutmaster, 1st Lagos Troops, 1923—1925.
Hon. Secretary, O.G.S (Sports Section), 1923—1925.
do. do. Scoutmasters' Conference, 1924—1925.
Chairman, Rover's Movement, 1923—1925.

### Bravo! Gallant Bede!

Our congratulation to Mr. S. E. Bede Wright for his promotion as Asisstant Chief Clerk at the Southern Nigeria Secretariat—Speed on, Bede ; there is room always at the top.

### Congratulations.

We learn that Mr. S. I. Samuel, M.B.E., of the Governor's Office, was promoted to the post of a Chief Clerk, as from 1st April last.

### Mr. Bright on leave.

Mr. E. Oluyele Bright, Head Clerk, Works, Manager's Office, Ebute Meta, is on 2½ months' leave of absence, commencing from 12th instant. He is expected to travel as far as Jos, Ife, Ondo, Kano, Aiyesan and then to Lagos.

### Meeting of the Leg. Co.

Legislative Council resumes sitting on Tuesday next, the 20th instant.

---

## NI IRANTI.

Ni iranti MRS. EUGENIA LABINJO ti No. 28, Luther Street, (Mọṣalaṣi Olosun) Eko, ẹniti o gbe ara-aiku wọ̀ lọjọ kẹrindilogun oṣu *October* leṣi, (1924).

B' o fẹ gba ohun ọwọ mi,
Ohun ti o ṣe ọwọn fun mi,
Ng o fi fun ọ, ṣe TIRẸ ni
Ṣe Ifẹ Rẹ.

---

Awọn Angẹli, poyika
Awọn Angel poyika
Nwọn ti mu, nwọn ti mu
Sister lo 'le.
Ọrun oni a san ẹ!

Eko, Ed.—"Eko Akete"
17th October, 1925.

---

## NI IRANTI.

Ni iranti Ẹni-ọwọ mi ọwọn
DAVID AUGUSTUS JONES
Ẹniti o pa ipo da ni ọjọ kẹrinla oṣu
*October*, ni ọdun 1918.

1. Daddy Jones, ma sun k'o si ma simi;
Gbori rẹ l aiya olugbala Rẹ,
A fẹ ọ, ṣugbọn Jesu fe ọ ju,
Sunre! sunre! sunre!

2. David Augustus Jones, ma sun ki ṣe titi
Ao tun pade nile mimọ loke
Nibiti ipinya ko ni si mọ
Sunre! sunre! sunre!

3. O ṣe! oninure wa fi wa silẹ lọ,
Awa ko ni gbagbe re titi lai
Fun ifẹ nla rẹ ti o ni siwa
Sunre! sunre! sunre!

4. Bi ina ba ku a feru boju
Bi ọgedẹ ku a f'ọmọ ropo,
Iwọ si ti f'awọn 'mọ rẹ ropo re,
Sunre! sunre! sunre!

PHILLIP TAIWO KUKU

*Telegraphic Address*:—" SERVICE LAGOS.
Telephone Number; Lagos 91.

ALL STANDARD CODES.

# THE SERVICE COMPANY.

POST OFFICE BOX 169,
BROAD STREET,
LAGOS

Service for all Nigerian Requirements.

DEAR SIR (or MADAM),

To ALERT and KEEN buyers of all classes of MERCHANDISE, whether small traders or traders on the largest scale, we beg to announce that the SERVICE COMPANY of LAGOS can offer goods at the lowest possible prices, of best quality and can give prompt and efficient despatch of the goods to all buyers.

LAGOS is the acknowledged centre for keen and competitive buying and we put it to you as PROGRESSIVE Traders that tc utilize our services, and thus purchase in the keenest market will enormously add to your profits and add largely to the number of your regular clients. We hold most of the principal stocks required for all classes of trading and where we may have run short, (and this happens when a shipment has been very popular and sold out almost at once) we will obtain it for you in the cheapest possible manner locally. We can also obtain direct from England or the Continent if you desire. Our system of satisfying all orders in this manner will save you much disappointment and also loss of time in execution which so often happens when orders are not sent to a CENTRAL DEPOT, to which is attached an efficient BUYING and FORWARDING DEPARTMENT, with a European in charge.

## Terms

Are Cash with Orders and sufficient over for Postage or Freights should be sent. Any balance will either be credited to your account in our books and advised to you or returned as you may request. Remittances may be made by Money Orders, Postal Orders, Bank Drafts or Currency Notes (the latter should be registered).

## Sample Parcels.

To those Traders who are just starting we offer to send a well assorted parcel of say £2, £3, or £5, all readily saleable lines. This you may either leave to our discretion or give an indication of the class of goods you would prefer. Good businesses are built up by starting with our sample parcels and every encouragement an advice of an expert European acquainted with this matters will be given to all beginners.

## Services.

Quotations for goods are sent almost by return of Post and in cases of Urgency a Reply Paid Telegram should be sent. Produce Prices ruling in Lagos will also be telegraphed free of charge if a Reply Paid Telegram is sent.

Should you require any PRINTING done in connection with your business we shall be pleased to receive an indication of your requirements when we will draft it for you, correct the proofs etc. In fact whatever Service you may require in Lagos we shall be happy to act for you.

With all good wishes for our mutual business relations and assuring you at all times of our best attention.

We are,

Yours very truly,

THE SERVICE COMPANY.

## IROHIN ABẸOKUTA.

### IWUN OJU WA LOJU RI, AF'AGO K'ẸYIN APARO.

Ni *Wednesday* ọjọ keje oṣu yi ni iwaju Baba Ẹgbẹ Ọlọla O. Ṣọwande ni Ake, a fi Ọgbẹni Amọdu si ẹwọn ọdun marun pẹlu iṣẹ aṣegan, fun ẹsun pe o gbe ọmọde kekere ẹjẹ ọrun kan ti ko ju ọdun mẹrin lọ s'ẹsẹ o si ba a ṣe nkan ti ko tọ, ọmọ na ṣẹṣẹ gba aburo ni. Ọdẹlesinmin yi ngbe abule kan ti ko jinna si Ọfada, ni igberiko Abẹokuta.

### AYỌ AYỌJU TI AKERE T'O FI ITAN ṢẸ, EYI ARA!

Tẹdun-tẹdun ni a fi gbọ iku ojiji Ọgbẹni A. Jolly Adecco Ọga-agba awọn Onimọto ti Ilẹ yi, a gbọ pe alayo yi rọ nkan sori tan ni alẹ Monde ọjọ karun oṣu yi l'alẹ, bi o ti mbọ lori Kẹkẹ-ologere rẹ, ni gẹrẹgẹrẹ ibi Ṣ ṣi Igbein si isalẹ ile rẹ, bẹni o f'ori sọ igi lojiji, bẹni gbogbo ori rẹ fọ tutu, nigbati iyawo rẹ nwa a bọ li o wa ba nibiti o nj'oro lọwọ. Nwọn ṣ'ājo gbe e lọ si ti Dokita, ṣugbọn ẹpa ko b'oro mọ. Jagun y'ayọ d'ọrun kẹndẹnrẹn lai w'ẹhin! Ki Oluwa fi ọrun kẹ ẹ!

### ARA ALANPỌ LO PỌ SI, T'ELEPO DIẸ.

A ba Ogbẹni J. S. Okunkẹnu kẹdun jọjọ fun awọn Ọsọlẹ ti o wọ'le rẹ ni alẹ Jimọ mọju Satide ọjọ kẹwa oṣu yi. A gbọ pe op lọpọ aṣọ adirẹ ati aṣọ oniyebiye ti nwọn ko fun u pamọ ni awọn igara wọnyi gbarabi rẹ lọ bambam. Ki Oluwa fi ọran mọ bẹ o! Amin.

### ỌMỌ N'AYỌLE, ẸNI ỌMỌ SIN L'O BIMỌ!

A ba Ogbẹni Akibọ ti Wasimi Ake, Apesi Itẹsi, kẹdun gidigidi ti iku ọmọ rẹ ti o ṣẹlẹ ni lolo yi; a gbọ pe ibiti ọmọ yi nwẹ lọwọ ni o di Ologbe si bambam! Ki Oluwa tun pese ti anfani, ki O si tọju awọn ti o ku n'ilẹ o. Amin.

### AYỌ A B'ARA TINTIN; Ẹ KU EWU O!

A ba Ogbẹni W. M. Ọlayọkun yọ gidigidi fun ọmọkunrin gidigbigidigbi ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ—Y nka lẹrẹ, ni Mọnde ọjọ karun oṣu yi. Ẹ ku ewu o!

### NKAN TI O ṢE KI S'ILE, SI TI ṢE KI S'ODE, EYI ARA!

A ba Ogbẹni J. Ọla Majiagbe kẹdun jọjọ ti iṣẹ ti o ti tẹ ẹ lọwọ labẹ Ijọba wa (Ẹgba *Native Administration*) nihin, gẹgẹ bi a ti rohin rẹ laipẹ yi si ti bọ lọwọ rẹ, lati *Tuesday* ọjọ kẹfa oṣu yi.
Oluwa a pese o. Amin.

### BABA RE'LE O! ILE LO LỌ KO W'ẸHIN!

Tẹduntẹdun ni a fi gbọ iku Daddy Paul Ṣokunbi ti Ikereku, baba Ọgbẹni Bandele Afolabi ti *Account Section* ni *Post Office*, l'Eko. Ọgbẹni na to ẹni ọgọrin ọdun tabi ju bẹ lọ. A ki awọn ọmọ Daddy Paul Ṣokunbi, ẹ ku aṣẹhinde o.

### A B'ỌBA GBE'LE NF'OJU D'OBA, EYI ARA!

Ni nkan ọjọ Alamisi ọjọ kẹjọ oṣu yi, Ọlọpa Ọba (*Nigerian Police No. G. 826*) ngun Baisikulu lai tanna ni alẹ, ti ikan ninu awọn Sikaọtu (*Scouts*) nihin da a duro, o si mu nọmba rẹ, o jẹ ki o mu u ni ọjọ keji o wa lọ sọ fun D.O. l'Oke Igbein, nwọn si wa Ọlọpa yi ti, gẹgẹ bi a ti gbọ.

D.O. wa sọ fun Sikaotu na pe ki o fi Ọlọpa silẹ fun on, bi bẹkọ, ki o lọ pe e l'ẹjọ.

Nkan ti o tun nwa ya ni lẹnu ninu rẹ ni pe nigbati o di ọjọ karun ti nkan yi ti ṣẹlẹ eyini ni Mọnde ọjọ kejila oṣu yi, ni Ọlọpa yi wa ni ọmọkọnrin Sikaotu yi fa aṣọ Ọba ya mọ on lara. Lẹsẹ kanna ni nwọn mu Waranti wa mu u ni nkan ago kan koja l'ọsan. Nitoripe ọmọde yi jẹ ọmọ Ile-iwe Giga nihin, lẹsẹ kanna awọn Ọga Ile-iwe ibiti ọmọde yi nlọ ti fi ẹsẹ si, bi bẹko, nkan ki ba ti ṣe sọ. A si dupẹ lọpọlọpọ lọwọ Alake Ọba wa Kabiyesi o! Ẹniti o sa gbogbo ipa rẹ pẹlu ti ọmọ na, ipẹkun rẹ ni pe nwọn ni ki a na ọmọ na ni ẹgba mẹrin fun aṣọ Ọba ti o faya, nwọn si fi Ọlọpa fun aitanna sinu baisikulu rẹ nigbati ina to tan.

Ẹnyin Ọmọ-ẹgbẹ Sikaotu ilẹ wa, ẹsọ d'owọ rẹ o. Bi a ba nkilọ fun ole, ki a ma kilọ fun ọmọ ẹba ọna. Ẹ jẹ ki oloku ru u lọ o!

A dupẹ lọwọ D.O. ti o rọra fi ibaralẹ wa ọran na ti o fi rọra pari rẹ sọnbolọku bayi "Nitori iru ti o ba le ni lori pete ati gbe ni mu.
Kabiyesi o!

### OLUWA YIO RẸ NYIN L'ẸKUN O!

Bi a ti nkọwe yi lọwọ ni a gbọ pe ọmọde jojolo ti Iyawo Ọgbẹni Ọlayọkun bi fun u ni ọjọ karun oṣu yi jalaisi. Oluwa fifun ni, Oluwa gba a lọ, ibukun ni orukọ Oluwa. Oluwa na yio pese t'anfani o. Amin.

Emi ni ti nyin nitootọ,

AWODI OKE.

## ETI ỌBA NILE ETI ỌBA LOKO.

Ẹsọ di ọwọ rẹ o, iwọ awo iwe kọwura Ibode (*Customs*) *Iddo*:

O jẹ ohun iyanu lọpọlọpọ lati ri Akọwe Ibode kan, ti awọn Ọlọpa nti gọgọ, lọsẹ ti o koja lọ si Ṣabu Baba Ẹgbẹ kekere ti o wa ni *Iddo*, fun ẹsun wipe wọn ri ọgo Ọti lọwọ rẹ. Ẹnyin ọrẹ wa ti o ku lẹnu iṣẹ Ibode (*Customs*) *Iddo* ẹsọ di ọwọ nyin o.

Jọwọ ba mi kọ orin yi fun awọn ọmuti:—

Ẹnyin ọloti, ẹ lọ yọti mu
Oloje npania
Oloje npania (2)
Ẹnyin ọloti, ẹ lọ yọti mu
Oloje npania.

## EMỌ! NKAN WA LEKO YI!

Irin gbe wa lọ si ọna Mọsalaṣi Olosun ninu ọsẹ ti o kọja, ni a ngburọ ariwo ẹrin: ni a wa ṣe iwere wipe nwọn gbe Iyawo ni, tabi ẹrin ayọtẹti wo lo kuku pọ to yi, ni ẹrẹ wa kan wa so fun wa wipe awọn Adeleb (*Women*) ọl dun meji mọ marun (*2 to 5 years*) ni wọn ko arawọn jọ ti wọn nṣe Ẹgbẹ "Gbajumọ Eko" Ẹsọ di ọwọ nyin o, ẹnyin abilekọ ọlọdun meji mọ marun. Ile Okọ obinrin nj awa mọ wipe o ni lati ma gbe. Ati wipe ile Ọkọ obinrin ni obinrin ni lati wa, ki o si ma ṣe fari tabi afẹ oriṣiriṣi ti o ba wu. Ẹsọ di ọwọ rẹ iwọ Anti Akona, tabi iwọ Iyawo titun ti o ṣeṣẹ de ile ọkunrin kan larin ọdun meji mọ marun. Gbadura iwọ Agan obinrin Ọlọrun na yio si da ọ lohun. *Amin.*

## IKU NṢE OHUN ARA.

Tẹdun-tẹdun la fi ki Ọgbẹni wa Oni-Orisan ti Obun-Eko ati awọn ẹbi rẹ fun iku aburo rẹ ti o ṣẹlẹ ni Alakoro ni lọlọyi, sisun ni aburo re sun. Ọlorun alanu yio ṣọ ile ati awọn ọmọde fun ẹ, ẹhin oku na yio dara. A si tun ni lati ki Mrs. Frank John ati Mr. Oni-Orisan fun inawo oriṣiriṣi ọjọ. Ẹhin Baba kekere yio dara o. *Amin.*

## ALAFIA KỌ NI ẸWA BI.

A ki Ọgbẹni wa onile oke "Ireti Cottage" ti Apọngbọn *Street.* Ọgbẹni wa yi nta oriṣiriṣi ohun elo iṣọ ile daradara. Ya ki o ra ti ẹ nibẹ aje aw a o. Alafia ko ni gbogbo ile wa bi?

## ṢIṢI ỌJA IKORE ṢỌṢI EREKO.

Ohun kekere ni a ti npe ri ṣugbọn nigbati a de ibẹ li a ri Aṣbẹjọro (*Lawyer*) Withnell Williams ati Ọgbẹni wa Agba C. A. King ti wọn nṣe bi alarira nipa ṣiṣi ọja ikore na, pẹlu owo *Pa:er* (*Currency*) ati owo Fadaka tamu-tamu. Ki Ọlọrun gbọwọ nyin soke o *Amin.* A si tun ni lati ki Iya wa Mrs. Ogunbode ati awọn ẹgbẹ rẹ ti a ko le daruko wọn tan si inu iwe yi, fun eto ohun jijẹ (*Chop*) aladidun oriṣiriṣi ti o ṣe si ori Tabili (*Table*) ni ọjọ na fun tita.

Adura wa ni, ki Ọlọrun ṣọ wa ka tun pade ni iwoyi amọdun, *Amin.*

## ỌLỌPA! ỌLỌPA!! O!!!
## IBOSI ỌLỌPA O.

Awa aladugbo *Luke Street*, ni ẹba ọja Ereko yio dupẹ lọpọlọpọ lọwọ Ijọba, ti wọn ba le fun awa aladugbo yi ni Ọlọpa kan ti yio ma ba wa ṣọ adugbo na nitori awọn ole nyọ wa lẹnu lojojumọ.

Jọwọ Mr. Kester *The Superintendent of Police*, ba wa ri si ọrọ ẹdun ọkan adugbo na. Mo ju ba o l Ọba (*King*) yio pẹ lori Oye o.

TẸNI-MASUN-WỌN.

---

## IROHIN LATI ILE-IFẸ.

### IKU.ORO RẸ DA, ISA OKU IṢẸGUN RẸ DA?

### JALA ADEPỌ (IYALODE ANIWURA), O DI GBERE.

Gudugbẹ ja ni Ile.Ifẹ nipa iku Jala Adepọ, Iyalode Aniwura ti Ile-Ifẹ, aburo Ob Oni ti ẹni to ṣalaisi ni ọjọ kokanla oṣu **October**, 1925.

Obinrin yi jẹ oninurere, ọloyaya, oniwa tutu, o si gbajumọ pupọ, o si jẹ arẹwa obinrin larin awọn obinrin ti nbẹ ni ilu na. Ọba Ọni ni Ile-Ifẹ na kutupu owo nigbati Iyalode wa ni dubulẹ aisan, ẹgbogi oriṣiriṣi npade ara won ni ile Iyalode, to njẹ, to nmu, ṣugbọn nigbati akoko Oluwa to, iku si pa oju rẹ de, ibukun ni fun Oluwa.

A ki Ọba Alaiyeluwa Ọni Ile-Ifẹ, Arẹmọ Jagbọdọ, Prince Adeyẹmi, Gabriel Adeyemi, Princess Adelaju, Soko ati ẹbi wọn gbogbo l'Eko awọn ọmọ ọmọ Olubode, nwọn ku ajalu, a si tun ki awọn Ijoye, ati gbogbo ilu, ẹ ku ọfọ, pẹlu ọmọ rẹ ọkọnrin kanṣoṣo to fi silẹ. Ki Oluwa ko gbe s'afẹfẹ rere.

OLUṢAKIN.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

CATHOLIC.

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yio ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)
Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.
(EVENING.)
(Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.
ST. MICHAEL'S ) Lafiaji.)
MORNING. 7—8 8.30—9.30
EVENING. 5.45—6.30

ANGLICAN

| *Time.* | | *Preacher.* |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church, | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 9 a.m | St. Paul's (Breadfruit) | The Curate |
| 6.30 p.m. | do. | The Archdeacon |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | do. |
| 6.30 p.m. | do | Rev. M. S. Cole |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. S. V. Latunde |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | W. A. Aiyedun |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. H. Ogunro |
| 6.30 p.m. | do. | |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | Rev. D. A. Bababunmi |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. J. A. Angus |
| 3 p.m. | | Bro. S. O. Stowe |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. S. A. Pearce |
| 7 p.m. | do. | Rev. E. E. Williams |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | do. |
| 7 p.m. | do | Rev. S. A. Pearce |
| | Williams' Memorial Wesleyan (Ebute Mẹta) | |
| 10.30 a.m. | | Rev. D. A. Tekoe |
| 7 p.m. | do. | do. |

AFRICAN

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Bro. J. T. A. White |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Christ Church (Ebute Mẹta) | Rev. E. Ayọ Salu |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. J. Ṣotayọ Williams |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. I. O. Oyekunle |
| 9 a.m. | Zion | Rev. N. J. D. Ṣomuji |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m | Salem Church (Ebute Mẹta) | |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 9 a.m. | Bethlehem Church (Ebute Mẹta) | |
| 7 p.m. | | |

| | | |
|---|---|---|
| 10. a.m. | African Methodist | Bro. E. A. Williams |
| 7 p.m. | do. | Bro. S. A. Falola |

BAPTIST

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ebenezer | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Ararọmi | Rev. A. A. Puddicombe |
| 6 p.m. | | do. |

ISHOLARIAN.

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Pastor A. Ọkọya |
| 7 p.m. | | Supt. A. Ibaru |

EPISCOPAL

| | |
|---|---|
| 9 a.m. & 4 p.m. | Patriarch J. G. Campbell |

AHMADIA

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodeinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. A[illegible]
(Central Mosque, Arọlọya Street.)

ZION CONGREGATIONAL

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Kakawa St. | Locum Tenens |
| 7 p.m. | do. | do. |

ARMY

10 a.m. Glover Memorial Hall
Capt. Jones and the cadets.
7 p.m. do.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Opne Air Service at Campbell Square
J. P. A. Taylor

AFRICAN FAITHIST KOSMON

5 p.m. 8, Shitta Street. Bro. A. Gbogbo[illegible]

---

## IGBẸ L'OWO WÀ.

### EKO.

Bi ǹwǹ Ekurọ, Epo ati *Cocoa* ti kun ọsẹ yi leyi:—

EKURỌ
£15 fun *ton* kan

EPO.
£26 fun *ton* kan.

COCOA.
£28—£31 fun *ton* kan.

### AGEGE.

COCOA.
£28—£36 fun *ton* kan.

"O di ọdun marundi-logoji nisinsinyi ti a ti bẹrẹ si ṣe *Mentholatum*, a si mọ ọ kakiri gbogbo aiye bi egbogi ti o wulo fun wiwo:—Otutu orişirişi, Ọna-ọfun ti o ndun-ni, Ori-fifọ, Arun Awọ-ori, ati gbogbo Arun Awọ-ara."




A HEALING CREAM

# Mentholatum

Mentholatum has been manufactured for 35 years and is known throughout the world as a medicine of great value for Colds, Sore Throat, Headache, Scalp Troubles and all skin ailments.

**THE MENTHOLATUM COMPANY LTD., SLOUGH, ENGLAND.**

*Over 16 million jars sold last year.*

**J. C. VAUGHAN**

Ti ile-ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna : bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ra nibẹ :

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanna. Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Atari-Ajanaku lọjọ to ti pẹ : bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai ! bi o ri orişirişi Ọkọ ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere ibẹ.

**GOOD MARKET.**

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes : these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods ! Superior Quality ! ! Quick Fortune ! ! !

RICHARD A. AJAYI,

*Fashionable Tailor.*

21, Moloney Bridge Street, Lagos.

Come for trial. Fitting Guaranteed

Charges very moderate.

When replying advertisers please mention *Eko Akete.*

**Saccharine! Saccharine!! Saccharine!!!**

*Purer than Sugar, Sweeter than Sugar, Cheaper than Sugar and more economical than Sugar.*

Try it in your Cup of Tea Coaca, Coffee or in your Oats or Paps, you run no risk.

Saccharine is absolutely harmless even to the most delicate system ; it is very good for young and old, it is now in use in many homes. " A boon to those who do not take Sugar and to travellers." If you are in doubt consult your physician.

1 Bottle of 600 Tablets for 1/3d.
1 " " 500 " " 1/-

*Good Bargains.*

Apply to the Manager :—

APALARA STORE,
72, Great Bridge Street,
Ẹnu-owa.

P.O. Box 772,
Lagos, Nigeria.

TO LET OR LEASE.

All that piece or parcel of land with the buildings thereon situate at 106, Denton Street, Oyingbo Market, Ebute Mẹta.

Apply to the EDITOR.

**Enia Soro Medicine and General Stores.**

SHAPON—ITOKU ROAD, ABEOKUTA.

Ẹ o ri ogun Ikọ, Atura ọkunrin ; ogun Ọrin, Igbẹ şoro, Inukikun, ti obinrin ko ba ri nkan osu rẹ ; Aitete loyun, Ewo, Apeta, Igbẹ ẹjẹ, Atọsi, Ẹda, ati orişirişi arun ti nba obinrin ati ọkunrin ja, lọ si ibẹ. Owo pọ ni wọn jasi.

ẸNIKEJI,

Aşọ oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3, *St. John Street,* l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

## KERE O!

Ọgbẹni M. Winnet Macaulay, ti Ita Oju-oto l'Eko, *(32. Vincent Street)* bẹrẹ iṣẹ Ẹrọ Alọgi; Ẹrọ na si ni agbara Ẹṣin mẹfa. Bi idan ni Ẹrọ yi fi nlọ Igbado; ẹnikeji o sekọ ni o, o ṣagita ni o, re danwo owo rẹ ko tani lara, ẹ tete mu Agbado nyin to lọ.

---

# Ero ya wa ra

ADEBOYE ṢOLANKẸ Oniṣowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Iṣo loriṣiriṣi, Kọkọrọ (Iṣika) t'ilẹkun ati t'apoti loriṣiriṣi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda loriṣiriṣi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọṣan, ati Pakun ti Awo-ẹja loriṣiriṣi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-ṣawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ṣọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

---

## Coffins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. Pereira's, Ṣẹtẹolu Compound, Odunlami Street, Lagos; also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

**Coffin! Coffin!! Coffin!!!**

With excellent workmanship and finish on sale at Paul I. Samuel's Workshop' 40, Campbell Street, Lagos.

PAUL I. SAMUEL,
*Builder & Contractor.*

Residence and Office 72, Igboṣere Road Lagos.

---

## Books Worth Reading,

On various subjects for Schools and Public Examinations.

Excellent Lectures, Essays, Novels, Dramas, etc. for General Readers and Book-Lovers and comprising Works of prominent English Authors.

R.P.A. Cheap Reprints from Thomas Paine, Ingersoll, MacCabe, Gorham, Herbert Spencer, Stuart Mill, Haekel, Bradlaugh, Huxley, Matthew Arnold, &c. Prices from 1d upwards.

Second-hand Books at about half the published prices; New Books at Bargain prices.

School and Office Stationeries.

Call on, or send enquiry to,

THE ORA BOOK SYNDICATE,
33, Ọbun Eko Street
LAGOS.

---

## KERE O!

Iya-afin Mrs. Beckley nṣu Akara didun *(Cake)* ta nile rẹ, ni 53, Opopo nla, ō gbeyawo ni o, rē yan tirẹ nibẹ; o sami fun ọmọ ni o, rē yan tirẹ nibẹ; o tọrọ ọmọ ni o, re yan tirẹ nibẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo rẹ.

---

TO LET.

# A. Kessler.

*THE INDENT HOUSE*

FOR ALL GOODS FOR THE WEST AFRICAN MARKET.

**7, Labinjo Lane,**

**Williams Street,**

***P.O. Box 459***

COME AND TRY ME!

FOR THE CONOISSEUR

## Crystall Beer Per Case

## 33s.

## Genuine Pilsener Urquell

**Per Case**

## 39s. 6d.

*BREWED IN PILSEN*

AND THE

## Padlock Brand Beer

*48 FULL-SIZED BOTTLES*

**Only**

## 40s.

Ẹniti ko ba wa ẹran rẹ a bi obukọ.

## The "B'yotiri" Mart

B. O. JOSEPH,

*Licensed Auctioneer, Commission and Es[tate] Valuer and Appraise[r]*

22, Church Street, Lagos Nigeria

(Near Carter Bridge)

Undertakes the sale of all kinds of goods an[d] properties either by private contract or public [sale] any part of Nigeria.

He is also willing to act as commission agent [to] the local firms.

*(Over 21 years' experience in trade.)*

**Cotton, Sundries, Hardware Provisions.**

Prompt rendering of accounts and quick re[turns]

Moderate Charges.

Sales on MONDAYS and THURSDAYS. Comm[encing] 9 a.m.

*Emergency Excepted*

Patronage is respectfully solicited.

The Mart and Office,
22, Church Street,
Lagos, Nigeria.

*Telegrams*
"BEN JOSEPH" La[gos]
*Residence*
35 Richards [Lane]
Lagos

## TO LET OR LEASE.

A very commodious shop suitable [for] commercial purposes, situate and be[ing at] No. 21, Bishop Street, Lagos, pre[sently] occupied by Messrs. G. B. Ollivant [&] Co., Ltd. and will be vacated on the [end] of October, 1925.

ALSO

A Land at No. 39, Patey Street, [E]. Metta, measuring 25 x 105 feet, su[itable] for residential purposes

For particulars apply to:—

B. O. JOSEPH,
*Licensed Auctioneer.*

The B'yotiri Mart,
22, Church Street,
(Near Carter Bridge)
Ebute Ero,
or 35, Richards Lane,
Lagos.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED [BY] ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.